# JESU NI OHUN GBOGBO FUN WA

## Kolosse 1:9-29; 2:8-19

## ẸKỌ 410 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Iwọ ti o da ọrun on aiye nipa agbara nla rẹ ati ninà apa rẹ: kò si ohunkohun ti o ṣoro fun ọ" (Jeremiah 32:17).**

**Alufaa Oloootọ Kan**

Ni gèrẹ́gèrẹ́ afonifoji odò Lycus ni Asia Minor ni ẹgbẹ́ awọn Onigbagbọ́ kan wà ni ilu Kolosse. Alufaa wọn oloootọ ni Epafra ẹni ti o n gbadura tọkàntọkàn ati pẹlu otitọ inu fun awọn eniyan wọnyii pe ki wọn le jẹ́ pipe ati ki wọn si wà ni kikún ninu gbogbo ifẹ Ọlọrun.

Awọn ẹsin èké ti farahàn ni Kolosse, nigba ti Epafra si ri i pe awọn Onigbagbọ́ wọnyii wà ninu ewu gbigbá wọn kuro ninu igbagbọ́ ailẹtan ninu Kristi, eyi mu un lọkan gidigidi. Nigba ti Epafra rin irin-ajo ọ̀na jijin lori omi lati bẹ Paulu wò ni Romu, o sọ gbogbo aini ijọ Kolosse fun Paulu.

**Iṣẹ-isin fun Ọlọrun**

Paulu wà ni ìtimọle gẹgẹ bi ẹlẹwọn, a dè e mọ́ ọmọ-ogun kan lati maa ṣọ ọ, ṣugbọn a kò de ẹmi rẹ̀. O n gbadun ominira ti o ni ninu Oluwa, Ọlọrun si ti ṣi ayè silẹ fun Paulu lati maa gbé ninu ile àdágbé ti oun tikara rẹ̀ nibiti o ti n kọ́ gbogbo awọn ti o tọ́ ọ wá lati mọ̀ nipa Jesu. O le jẹ ninu ile yii paapaa naa ni Paulu ti kọ awọn iwe wọnni ti o jẹ́ iṣiri ati iranlọwọ fun awọn Onigbagbọ́ nibi gbogbo.

Ẹ jẹ ki a ṣe ayẹwo igbesi-ayé Paulu ninu iṣẹ-isin rẹ̀ fun Ọlọrun nigba ti a ba ri idanwo ti o le mu wa wi pe a kò lagbara lati ṣe eyi tabi eyini ninu iṣẹ Ihinrere. Bi o tilẹ jẹ pe a jẹ́ alailagbara nipa ti ara, ti a kò ni ọrọ̀, a le ṣe alaini talẹnti pupọ, sibẹ a maa n ni iṣiri nigba ti a ba rònu nipa ti Paulu. O ni ailera ninu ara, bẹẹni kò si ni owó bikoṣe kiki eyi ti oun gbà ninu iṣẹ agọ-pipa ati eyi ti awọn ọrẹ rẹ̀ ba fun u. O ti jẹ́ ẹlẹṣẹ ri nigba kan, o si wa di ẹni ti o le ṣiṣẹ fun Ọlọrun nitori o ti jọwọ ayé rẹ̀ fun Jesu Oluwa. Awa pẹlu, nipa iranlọwọ Ọlọrun, le ṣe bẹẹ gẹgẹ.

**Imọ Ọlọrun**

Epafra royin fun Paulu nipa igbagbọ́ ti awọn ara Kolosse ni ninu Kristi Jesu, ifẹ ti wọn ni si ara wọn, ati ireti aaye ti wọn ni nipa Ọrun. Nigba ti Paulu gbọ́ iroyin rere yii nipa ifẹ ati igbagbọ́ wọn, o gbadura fun wọn. O kọwe lati mu wọn lọkan le lati gbadura si Jesu fun iranwọ.

Ohun kin-in-ni ti o leke ọkàn Paulu ni pe ki awọn Onigbagbọ́ ti o wà ni Kolosse le mọ ifẹ Ọlọrun ki wọn si ni ọgbọ́n Ọlọrun gẹgẹ bi a ti fihàn ninu Bibeli. O gbadura pe ki wọn le ni oye ohun ti ẹmi. Lati mọ ifẹ Ọlọrun ati lati ṣe e yoo ràn wọn lọwọ lati le rìn, tabi lati gbé igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi Onigbagbọ́ tootọ, wọn yoo si jẹ iyin ati ibukun fun Ihinrere. Bakan naa ni o ri lode oni: lati mọ ifẹ Ọlọrun ati lati ṣe e yoo mu ki ẹyin ọmọkunrin ati ọmọbinrin ti i ṣe Onigbagbọ́ gbé igbesi-ayé ti o wu Oluwa ni gbogbo ọ̀na.

**Iyè Ainipẹkun**

Paulu gbadura pe ki awọn ara Kolosse le so eso ninu iṣẹ rere gbogbo, itumọ eyi ti i ṣe pe ki wọn le lo gbogbo anfaani ti o ba ṣi silẹ fun wọn lati ṣiṣẹ fun Oluwa. O gbadura pe ki wọn le pọ̀ si i ninu imọ Ọlọrun, ki wọn si maa kọ́ ẹ̀kọ́ si i nipa Rẹ̀. Njẹ o mọ ère nla ti imọ Ọlọrun n mú wá? O maa mú iye ainipẹkun wá, nitori Jesu tikara Rẹ̀ sọ ninu adura Rẹ̀ si Baba: "Iye ainipẹkun na si li eyi, ki nwọn ki o le mọ̀ ọ, iwọ nikan Ọlọrun otitọ, ati Jesu Kristi, ẹniti iwọ rán" (Johannu 17:3).

A mọ̀ nipa Ọlọrun nigba ti a wa ni ọmọde. Lọjọ kan Ọlọrun yoo dá wa lẹbi ninu ọkàn wa fun iwa aitọ́ ti a hù. Bi a ba purọ, bi a binu, ti a si lu arakunrin wa, Ọlorun yoo mu ki a mọ pe a jẹbi. O n fẹ ki a gbadura ki a si bẹ Ẹ pe ki O dariji wa ki O si gbà wá là. Nigba ti a ba dagba to lati ka ọrọ Bibeli ki o si yé wa, a o kà gẹgẹ bi Ọlọrun ti fẹ wa ti O si fi Ọmọ Rẹ̀ Ayanfẹ kanṣoṣo fun wa lati kú fun wa. A o ri kà bi Ọlọrun ti kún fun iṣeun; bi o ṣe jẹ́ Ọlọrun rere ti i si i ma fi ikẹ ṣe itọju ẹni kọọkan wa. Lẹyin eyi a o kọ́ nipa iṣeun Ọlọrun nipa iriri. Nigba ti a ba wà ninu wahala a ó gbadura si Ọlọrun yoo si ràn wá lọwọ.

Nipa awọn ọna bayii: idalẹbi fun ẹ̀ṣẹ, nipa igbala, nipa kikà ati nipa kikọ́ Ọrọ Ọlọrun, nipa iriri, imọ̀ wa nipa Ọlọrun yoo maa dagba si i.

**Ipamọra Pẹlu Ayọ̀**

Paulu gbadura pe ki wọn le jẹ́ alagbara ninu suurù ati ipamọra. Lati inu ọ̀kan ninu awọn ẹ̀kọ́ Jesu, "Ninu sũru nyin li ẹnyin o jère ọkàn nyin" (Luku 21:19), a kọ́ ẹ̀kọ́ pe suuru ṣe pataki ninu igbesi-ayé Onigbagbọ́. A nilati ni suuru pẹlu awọn nnkan ati ohun ti o n ṣẹlẹ; a nilati ni ipamọra pẹlu awọn ọrẹ ati awọn ẹlẹgbẹ wa.

Nigba ti iṣẹ́ yin kò ba lọ deedee mọ́, nigba ti ẹyin ọmọkunrin ba n kọ́ ile ẹyẹ, ti oòlù si sé lu yin ni atampakò tabi ti iṣọ ti ẹ n kàn bá tẹ̀, bi adura Paulu ba ṣẹ ninu igbesi-ayé rẹ iwọ o dakẹ́jẹ iwọ ki yoo si binu. Nigba ti awọn ọrẹ rẹ kò ba fẹ́ lati ràn ọ lọwọ, ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni ile-ẹ̀kọ́ purọ mọ ọ, iwọ yoo gbadura fun wọn. Ni gbogbo igba ti gbogbo nnkan wọnyii ba n ṣe lodi bẹẹ, iwọ ki yoo bẹ̀rẹ si ikaanu fun ara rẹ; iwọ o kún fun ayọ̀ iwọ o si dupẹ lọwọ Ọlọrun pe igbesi-ayé rẹ yoo buyin fun Ọlọrun ati fun Ihinrere.

**Olugbala Wa**

Jesu ni ipilẹṣẹ ati opin igbala wa. Oun ni ipilẹṣẹ nigba ti o ba dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa ti O si fi Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye bo ẹ̀ṣẹ wa mọlẹ. Oun ni opin tabi ipari igbala wa nigba ti O ba de ninu ofurufu lati mú wa lọ pẹlu Rẹ̀ titi lae.

Jesu ni aworan Ọlọrun. Baba ti a kò ri. Jesu farahàn bi eniyan ninu ibujẹ ẹran ni Bẹtlehẹmu (Heberu 1:6). O gbé ni Palẹstini O si rin kiri nibẹ pẹlu, O kú lori Agbelebu, O jinde kuro ninu okú, O si goke re Ọrun. A mọ̀ nipa Jesu nitori awọn ti o ba A gbé nigba ti O wà ni ayé kọ akọsilẹ nipa Rẹ̀, a si kà a ninu Bibeli. Gẹgẹ bi Jesu ti ri gan an ni Ọlọrun ri –oninuure, alaanu, olufẹ (Heberu 1:3).

**Ẹlẹda**

Jesu ni akọbi ninu gbogbo ẹ̀dá. Eyini ni pe, Oun ti wà ki a to dá ẹnikẹni ninu awọn eniyan. Jesu ti wà lati ayeraye. Ohun ijinlẹ ni. Kò le yé wa, ṣugbọn a gbagbọ́ nitori Bibeli kọ́ wa bẹẹ. Jesu wà pẹlu Ọlọrun nigba dida ayé, Oun pẹlu Ọlọrun ni o si dá ohun gbogbo (Heberu 1:10; Johannu 1:3). Oun ni o da ohun gbogbo ti o wà loke Ọrun ati ninu ayé -- oorun, oṣupa, ati awọn irawọ; koriko, awọn igi ati itanna; awọn ẹranko ati ohun alaaye gbogbo. Oun ni o si dá awọn nnkan ti a kò le fi oju ri pẹlu -- aṣẹ ati ijọba, tabi awọn orilẹ-ède. A kò le ri aṣẹ tabi ijọba, ṣugbọn a mọ pe wọ́n wà. Ohun gbogbo wọnyii ni Jesu tikara Rẹ̀ ti dá ati fun igbadun Oun tikara Rẹ̀ (Ifihan 4:11), ati nipa agbara Rẹ̀ ni ohun gbogbo wọnyii fi wà sibẹ ti a si so wọn pọ̀. Awọn igbekalẹ ẹ̀kọ́ atọwọda ọmọ-eniyan wà nipa bi ayé ti bẹ̀rẹ eyi ti o lodi si Bibeli, ṣugbọn lai ka ohun ti iwe akọsilẹ ẹ̀kọ́ eniyan wi si, awa mọ̀ pe Bibeli jẹ́ otitọ (Romu 3:4).

**Olori Ohun Gbogbo**

Jesu ni Ori Ijọ, pẹlu. Ijọ yii ki i ṣe ile-isin nibiti a ti n sìn. Eyi yii jẹ Ijọ ti a ko le fi oju ri, awọn eniyan Ijọ naa si ni olukuluku ẹni ti a gbala. Eyi ni Ijọ Akọbi, awọn ti a kọ orukọ wọn ni Ọrun (Heberu 12:23). Ki ni ohun ti iwọ rò pe o mu ki o wu Ọlọrun lati fi Jesu ṣe Ẹni ti o ga julọ, Ẹnikan ti o ṣe pataki julọ, Ori ohun gbogbo? Nitori Jesu ṣetan lati kú ki O si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lori Agbelebu lati mu eto Ọlọrun fun igbala ṣẹ. Ifẹ inu Ọlọrun ni pe ki a le mu gbogbo eniyan ati ohun gbogbo, ati awọn eweko ati awọn ẹranko pẹlu, pada bọ̀ sinu iṣọkan pẹlu eto Rẹ̀ fun gbogbo ayé gẹgẹ bi o ti ri ni Ọgba Edẹni. Jesu mu ki eleyi ṣe e ṣe nigba ti O kú fun ẹ̀ṣẹ wa.

**Fifihàn Lailabuku**

Awọn ara Kolosse, ti wọn ti jẹ ẹlẹṣẹ buburu nigba kan ni a ti mú wà ni irẹpọ didun ti wọn si di ọrẹ pẹlu Ọlọrun nipasẹ ikú Jesu lori Agbelebu. Nigba ti akoko ba tó fun wọn lati ṣiro bi wọn ṣe lo igbesi-ayé wọn, Jesu yoo mú wọn wà ni ailabuku ni iwaju Ọlọrun bi wọn bá duro ninu Ihinrere sibẹ. Yoo ṣe bakan naa fun wa pẹlu bi a ba wà ninu igbala sibẹ ti a si duro ninu Ihinrere Jesu. Nibomiran Bibeli sọ fun Onigbagbọ́ pe Jesu "le pa nyin mọ́ kuro ninu ikọsẹ, ti o si le mu nyin wá siwaju ogo rẹ̀ lailabuku pẹlu ayọ nla" (Juda 24).

**Ireti Ihinrere**

Paulu kọ́ awọn eniyan naa pe o yẹ ki wọn fi gbongbo mulẹ ki wọn si fi idi kalẹ ninu igbagbọ́ ki a má si le gbá wọn kuro ninu ireti Ihinrere. Ki ni ireti Ihinrere? Eyi nì ni pe lọjọ kan a o wà ni Ọrun lati jẹ alabapin ninu ogo ti Jesu ni pẹlu Baba. Paulu wi pe, otitọ pe Jesu n gbe ninu ọkàn awọn ẹni

irapada Rẹ̀ jẹ́ ohun ijinlẹ. Dajudaju a ko mọ ọna ti Jesu gba lati maa gbé inu ọkàn wa, ṣugbọn a mọ̀ pe O n gbe inu ọkàn wa nitori a n roye ifarahàn Rẹ̀ ninu wa. Bi a ba ṣi ọkàn wa payá lọna ti Jesu le gba maa gbé ninu ọkan wa nigbagbogbo, lọjọ kan a o wà ni Ọrun pẹlu Rẹ̀.

**Awọn Ẹkọ́ Eke**

Iwe Paulu n kilọ fun awọn ara Kolosse lati ṣọra lọdọ awọn ti wọn n fẹ lati mu wọn kuro ninu igbagbọ́ ailẹtàn ninu Kristi, ti wọn si n fẹ mu wọn gbẹkẹle ìmọ tabi èro ti eniyan -- àṣa ati igbagbọ́ ti awọn eniyan tikara wọn gbé kalẹ fun igbala ọkàn. Ọpọlọpọ eniyan ni kò fẹ rẹ ara wọn silẹ lati gba ọ̀na ti Ọlọrun là silẹ fun igbala ọkàn, ọ̀na "ti o ntàn siwaju ati siwaju titi di ọsangangan" (Owe 4:18); nipa bẹẹ wọn a gbé ọ̀na ti ara wọn kalẹ, ṣugbọn okunkun ati idarudapọ ni ọ̀na yii n yọri si.

A kilọ fun awọn Onigbagbọ́ ni pataki nipa awọn wọnni ti wọn n wi pe a nilati pa ilana ati eto isin Ofin Mose mọ́, nigba ti Bibeli wi pe "nipa iṣẹ ofin, a ki yio dá ẹnikẹni lare niwaju rẹ̀" (Romu 3:20). A kilọ fun wa lati ṣọra lọdọ awọn ti wọn kò gbà pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe ẹni ti o wá si ayé lati kú ati lati jinde, lati le gbà wa kuro ninu ẹ̀ṣẹ nigba ti Bibeli wi pe, "Ẹnikẹni ti o ba jẹwọ pe Jesu Ọmọ Ọlọrun ni, Ọlọrun ngbé inu rẹ, ati on ninu Ọlọrun" (1 Johannu 4:15). A kilọ fun wa nipa awọn wọnni ti n wi pe kò si ẹ̀ṣẹ ati pe èṣu jẹ apẹẹrẹ iwa buburu ṣaa ni, nigba ti Bibeli wi pe, "Gbogbo aiṣododo ni ẹ̀ṣẹ" (1 Johannu 5:17), ati pe, "Eṣu, ọtá nyin, bi kiniun ti nke ramuramu, o nrin kãkiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri" (1 Peteru 5:8). A kilọ, pẹlu, fun wa pe ki a ṣọra lọdọ awọn ti o gbagbọ́ pe aawẹ, jijẹ awọn oriṣi onjẹ kan, tabi ṣiṣe eré idaraya tabi ṣiṣe aṣaro le mu èrè wá, nigba ti Bibeli wi pe: "Ijọba ọrun ki iṣe jijẹ ati mimu; bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ ninu Ẹmi Mimọ́" (Romu 14:17); ati pe, "titọ́ si ohun ti ara, ère fun ohun diẹ ni, ṣugbọn iwa-bi-Ọlọrun li ère fun ohun gbogbo, o ni ileri ti aiye isisiyi ati ti eyi ti mbọ̀" (1 Timoteu 4:8). Ati li opin gbogbo rẹ̀ a kilọ fun wa nipa awọn ti kò gbà Kristi ni "Ori, lati ọdọ ẹniti a nti ipa orike ati iṣan pese fun gbogbo ara, ti a si nso o ṣọkan pọ, ti o si ndagba nipa ibisi Ọlọrun."

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni Paulu gbadura pe ki awọn Onigbagbọ́ Kolosse ki o kún fún?

2 Ki ni awọn ohun meji ti o gbadura pe ki a sọ wọn di alagbara ninu rẹ̀?

3 Aworan ta ni Jesu i ṣe?

4 Ta ni Jesu wà pẹlu rẹ̀ nigba didá ayé?

5 Ki ni ṣe ti Ọlọrun Baba fi Jesu ṣe ẹni ti o ga julọ tabi Ẹni kanṣoṣo ti i ṣe Ori?

6 Ki ni ohun ijinlẹ Ihinrere?

7 Lọdọ awọn wo ni Paulu kilọ fun awọn ara Kolosse lati ṣọra?

8 Ki ni itumọ ìmọ eniyan? Ki ni a n pè ni itan atọwọdọwọ?

9 Ta ni i ṣe Ori fun ara Ijọ awọn Onigbagbọ́?